# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ORE AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 712 FRIDAY, JUNE 5, 1964 (2D)


## Awon Alapata Ko Ni Pa Eran Ni Ọla

EKO:- Ni deede agogo mẹjọ owurọ ana ni irohin kan wa pe, gbogbo awọn Alapata Ẹran ko ni pa ẹran ni ọla ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹfa osu yi.

Irohin fi ye wa pe, ko ni si aye fun gbogbo awọn Alapata lati pa ẹran malu ti nwọn nta lọja ni ọla, nitori are Agogoro ẹyọ ti nwọn fẹ ṣe ni Eko.

Awọn ẹlẹran na sọ pe awọn ko ni pa ẹran ni ọla, nitori are Ẹyọ na

Awọn Oniwe Irohin Imọlẹ kesi gbogbo awọn obinrin ati awọn Iyawo Ile lati tete lọ ra ẹran lọja ni owurọ yi nitoripe awọn Alapata ko ni pa ẹran ni ọla. A ko si fẹ ki gbogbo ẹnyin ara ilu ke abamọ.

Ẹnyin ti o jẹ obinrin, ti ẹ ba ti ka iwe yi tan, ni ki ẹ tete lọ ra ẹran lọja bakanna ni a fẹ ki iwọ ti o nka iwe yi sọ fun gbogbo awọn ara ile ati aladugbo pe ko ni si ẹran lọja lọla.

Ṣugbọn awọn ẹlẹran na yio pa ẹran ni ọtunla, Ki Ọlorun sọ gbogbo wa ju ọtunla lọ o. Amin.

## Itakun To Ni K'Erin Ma Wọ'do, On Erin Lo Nlọ

# OKPARA LỌ BA ẸKUN NI IBUBA, O KA AKINTỌLA MỌLE !!

IBADAN:— Gbogbo enia bẹrẹsi sare akọlukọgba tẹle ara wọn lẹhin nigbati nwọn gbele gbọ pe Dokita Michael Okpara, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati olori ẹgbẹ Alakukọ nlọ ṣe ibẹwo Oloye S. L. Akintọla Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati Olori ẹgbẹ Dẹmọ ni irọlẹ ana.

Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn ara ilu nsare jade ti awọn ti njẹun lọwọ si pa onjẹ wọn ti si ẹgbẹ kan lati lọ sare woran bi otitọ ni tabi awada.

Onirohin wa fi ye wa pe, m ọ t o akero mejidinladọta pẹlu ọlọpa mejilelọgbọn lo wa ninu mọto awọn ọlọpa kọọkan ti nwọn mu ponpo lọwọ ti nwọn si de fila irin ni nwọn tẹle Dokita Okpara lẹhin



Dọkita M I Okpara

Mọto awọn Ọlọpa mẹfa lo ba Okpara de Ibadan ni ijẹrin, ṣugbọn nigbati o de Ibadan, ni awọn Ọlọpa Ibadan ba tun tẹle Dokita Okpara lẹhin pe, awọn ko ni jẹki ẹṣinṣin ba le e titi ti yio fi pari irinajo rẹ si Ipinlẹ Iwọ Orun.

Nigbati o di agogo mẹta ọsan o kọja iṣẹju mẹta, ni Dokita Okpara de ile Oloye Akintọla, ti o si kan ilẹkun ile rẹ.

Bi Dokita Okpara si ti ṣe de ile oloye Akintọla, ni awọn ọlọpa meji kan ba ṣure jade, ti nwọn sii sọ fun Dokita pe oloye Akintọla ko si nile.

Dokita Okpara ko le gbe mọto rẹ wọle nitoripe nwọn ti ilẹkun ọna ti mọto le gba wọle ṣugbọn o sọ kalẹ ninu mọto rẹ osi fi ẹsẹ rẹ rin wọle. Dokita Okpara sọ pe, e ṣe, ẹ ko tilẹ fẹ si aga randi nyin fun mi lati wọle?

Lẹhin ti awọn ọlọpa ti nwọn nsọ ile oloye Akintọla ti sọ fun tan pe, ko si oloye Akintọla nile, ni nwọn wa fun Dokita Okpara ni iwe ibẹwo awọn alejo lati kọ ohunti olẹ ba oloye na sọ. Dokita Okpara gba iwe na o si kọ ohun ti o fẹ kọ sinuiwe na gbogbo wọn si pada sẹhin.

Oniwe irohin wa be re lọwọ ọmọ kan ti o duro ni ẹhinkule ti o nwo awọn enia na ni ọkankan pe, "Nibo ni Baba lọ?" Ọmọ na sisọ fun un pe, "Baba wa nile, ṣugbọn nwọn nsun lọwọ"



Oloye Akintọla

Ninu awọn enia ti nwọn tẹle Dokita Okpara lẹhin lọ si ile oloye Akintọla ni Dokita K. O Mbadiwe oloye Olu Akinfosile·

WO OJU EWE KẸFA

## Bawo Lo Ti Dun To, Ki A Jijọ Maa Gbe Ni Irẹpọ ?



Aworan oke yi ni ti Iyaafin Oloye Awolọwọ ti on pẹlu Okpara nigbati awọn mejeji fẹ jijọ mu ot i- omi ọsan tutu ninu ile Oloye Ọbafẹmi Awolọwo ni Oke-Ado Ibadan, nigbati Dokita Okpara de Ibadan ti o lọ bẹ Iyawo Oloye na wo ninu ile rẹ.


**For Sale**

Jeep Land Rover with Good Condition Apply to:—

**Mr. Adeniji**
16, Bamgboṣe Street, Lagos.

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU Apa (14)

Ka pa ti awada ti irun gbọn rẹ dabi irun ẹṣin o mu herehere bi waya (wire) ti ko ba fẹ ki enia r'oju rẹ a ma a fi bo oju. Nigbati awọn Ọmọ Onilogbo rii, wọn mi pe eleru-a-sung ati pe Ogboju-le- Ogun lo fa a.

Alijannu yi bẹrẹ ọrọ rẹ bayi pe "Bi iya nla ba gbe ni ṣanlẹ keekeeke ami agori eni Iba ma ṣe bẹ ni iwọ apa ẹjọ mi. iwọ asi tun me a ba iyawo mi tage ninu ile mi"

Bi a o ba ku ẹkanṣoṣo laa ku. Ọmọ araiye asi gbe ni sin, ma f'oko mi da ọna, ẹkan so la nkọ Lẹhin iku sare ni ko to wi bayi tan. o ti lewo ija kaka ki Ogboju-le-Ogun baa ja. o bẹrẹ si bẹ ẹ pe ki o dariji on gẹgẹbi ẹnyin paapa ti mọ pe, bi ẹlẹbi ba ti mọ pe on jẹbi oye ki a dariji ni. Ibinu ka loju Alujannu yi, o si dariji ni. Awọn Ọmọ Onilogbo pẹlu Alujanu yi wa di ọrẹ timọ timọ nwọn mura lati mu irin ajo wọn pọn lọjọ na, sugbọn ko gba o ni on nfẹ ki nwọn sun ti on d, Ọjọ keji ki on si ṣe wọn lalejo, ki nwọn si jọ gbadun ati wọn ki nwọn to ma a lo, nwọn gbọ, nwọn si gba.

Nigbati ilẹ ṣu, o to nkan bi agogo mẹjọ alẹ, alujannu Oloju kan yi paṣẹ pe ki a gbe onjẹ awọn alejo sori tabili Ti iyawo Agidi lati kọkọ nsọ ri, pe o mọ ọrẹ ṣe ti iyawo Alujannu wa pa bambari, orun ọbẹ rẹ, ti enia ba ti fa asi imu lẹkan Oluwa rẹ yio yọ de Ọrun.

Irohin ko to afojuba ni onjẹ alẹ ọjọ na ko ni kan to, koti ni dun to ti nko ba jẹki ẹmọ iru ọbẹ ti iyawo Alijọnu yi se,

Awo mẹfa ni ogbe si ori tabili ekini kun fun Iyan ti pọn lọdẹdẹ nitori isu alọ lo fi gun un ko ni ẹyọ koko kan rara.

Ekeji jẹ awo ọbẹ. Owe (sikito owe lọkọ iyan) ode ade ẹgusi, owa fi yarin seti gbogbo rẹ di ṣikiṣiki awo ẹkẹta ajẹ ti ọbẹ aparo-asepọ mọ na, ẹnyin onkawe mi si ti mọ pe ẹniti oba f'aparo



Eṣu re e! Balẹ Ọrun Apadi!!

dala loni ni ki aṣi yan je awo ẹkẹrin jẹ ti ọbẹ igbin, awo karun ti ọbẹ dindin, awo kẹfa wa jẹ ti amala lafuu.

A gbe eyi kalẹ nitoripe boya ninu wọn ko ni mọ ẹ.

Gbogbo rẹ wadi kan ikani Alijọnu wa nsọ fun un pe ki awọn ma jafara nitori ọrọ wa atipe ilẹ nṣu lọ. Nwọn bẹrẹsi wẹwọ lokọkan nigbati nwọn wẹwọ tan gẹgẹbi aṣa onilogbo. Ige bẹrẹsi gbadura o ni "Busi fun wa Oluwa ki o si jẹki onjẹ yi mu wa lara le ki ale ma sin ọ nipaṣẹ nipaṣẹ Jesu Kirisiti Oluwa wa (Amin).

Lilaju ti awọn laju ni Oluwa fi han Ige gbangba pe majele mbẹ ninu onjẹ ti nwọn gbe niwaju wọn, Ige sọ fun awọn aburo rẹ nwọn ko ba nwọn fi nṣe ẹlẹ bẹni oba pe aja kan ti ọ nre gọja agba! agba!

Obu okele kan ninu onjẹ na o,u si aja na koiti gbe mi tan ti o fi di ologbe. Niko si jẹ onjẹ na mọ. Ebi bẹrẹ si pa wọn, nwọn rọ kale ati ori ọkọ rẹ, ogbe nwon

Obirin yi ti takete nibi ewe ẹdundun, ati sunto nwọn ko ri Orun sun, nitoripe ebi npa wọn.

gbayi ni awọn ọmọ ẹhin rẹ

Ogboju-le-ogun ṣẹṣẹ wa ranti pe gari olowoyọ kan wa lapo on, nwọn da somi, nwọn mu u yo, ni nwọn ba sun lẹ gbadari. O fa ṣẹrin kan yọ ninu apo rẹ, o gba a mọlẹ. Eyi yi jẹ ionfọn nti fọn, a sun ma parada ni ti igi aja ilẹ ni bẹrẹ si yniyin si.

Gbogbo wọn sun lọ bamu bamu, ẹnikẹni ko taji



Lati Owọ J. O. Shoyinka

Gẹgẹbi ẹnyin paapa ti ao pe, awọn jagunlabi wọnyi ti i fi malu, ewurẹ, tabi agbo ṣe ajọyọ a fi enia abirun lori.

Inu Alujannu ọloju kan dun to bẹ gẹ, nitoripe o ti [illegible] o ya fi dijẹ.

Ẹṣẹpe ṣimuṣimu. Awọn iwin joko sẹgbẹ kan pẹlu olori wọn iroko, awọn Alujannu joko sẹgbẹ kan pẹlu olori wọn, arọni, awọn iwin odo joko sẹgbẹ kan pẹlu olori wọn Yemọja, awọn iya mi Ọṣọronga joko sarin pẹlu olori wọn Ayun Ọrunbọ.

Ipade bẹrẹ, gbogbo nwọn pa lọlọ igba, kolu Alaga ọjọ na ni Ayọrunbọ (eiye buburu ti nje larin awọn ajẹ), Igbakeji alaga ni Ogun (lakaiye Ọsinmọle Olomirirole fẹjẹ wẹ), awọn ọgbẹni iwin Iroko, sọnpọnna, ati awọn Irunmọle mẹrinlelogun lo ṣe isọngbe rẹ lọjọ na.

Eṣu lolu okiri ẹko ni nwọn fi ṣe Ọlọpa (Police) nitope ọmọ ina la iran si ina. Eṣu kapa daru-daro nitoripe on le rda silẹ.

Ogun gbadura ṣoki, bẹni nwọn bi bere Ipade, Ayọrunbọ dide gẹgẹbi alaga lati ba nwọn sọrọ. Oni gbogbo ẹyin ti owa sibi Ipade yi ni mo lorukọ mi ati awọn ẹlẹgbẹ mi ti nlo ni ọrun alakeji, awọn wọn yi ko le bawa pejọ, loni, nitoripe o ni ni ọjọ ti kude degbo nṣe ọjọ ibi, enikẹni niran nwọn ko gbọdọ fi ọrun Alakeji silẹ ki nwọn ma baa ri ibinu iku oni emi ti mo wa larin nyin nisisiyi nko ni pẹ lọ, toripe mo jẹ ọkan ninu awọn ti iku fi pe wa sibi ase nla yi animọ ni peregun nlaṣọ ako ni pẹdin lailai, enia ko ni pa wa, ako si ni p'enia gbogbo wọn ṣe Amin.

Ṣugbọn Eṣu ati Ogun ko ṣe Amin Ayunọrunbọ tun dupẹ lọwọ wọn fun Alaga ti nwọn fi on ṣe Bi o ti sọro tan o joko.

Ogun bẹrẹ si sọrọ o ni, on dupẹ lọwọ Ayọrunbọ fun ọrọ ti on sọ. n tun dupẹ lorukọ no ati awọn ẹlẹgbẹ on. Ti Ayunọrunbọ bade ọrun alakeji ko ki Iku dedẹegbo ati ile ohun ajẹigba enia ma wukọ ẹgbọn rẹ, pe nwọn ku ajọyọ ọjọ oni, Oluwa a jeki nwọn ṣe ọpọlọpọ rẹ, o tun dupẹ lọwọ awọn ẹlẹgbẹ rẹ, to wa sibi ipade ijoko.


## Iyipada Ile Iṣẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti lọ si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan ẹ kọwe si ile itaja wa ni Nomba 1, Ishiba Street Odo

**Apejuwe Ile Iṣẹ Wa**

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba


**Ẹ ma ka Irohin Imọlẹ Oloyin-Mọmọ lojojumọ.**

# IWE SI OLOTU

## Mushin Nfẹ Ọlọpa Aṣọmọto

Olotu ... mi yio dun pupọ lati kọ iwe mi yi si nyin inu mi yo si tun dun ti ẹ ba le ba mi tẹ jade ninu iwe nyin to nko wa ni ọgbọn ati oye lati ba ọga ọlọpa ilu Mushin sọrọ lori awọn to nwa bọlẹkaja ori iwe aidara ti nwọn nhu loju ọna Mushin Agege

Mo fẹ ki ọga ọlọpa ran wa lọwọ lati fi ọlọpa si oju ọna Mushin lati mọ dari awọn awamọto paapa awọn to nwa Bọlẹkaja nitoripe oju ọna ni nwọn ti mọ gba ero bi nwọn ko ba gba ero tan nwọn ko ni ṣi rara

Nipa ṣiṣe bayi o nde ... awọn enia to nkanju ... ise duro ẹlomiran ninu awọn toni moti ko fẹ mọ gba Mushin mo nito ri dadura ... nje ki nwọn pe ki nwọn to de ibi ise wọn.

Ni asiko ti awọn Ọlọpa nduro si oju ọna, ko si iru iwa aidara yi rara, awọn onimọto ko njaja rara alafia ss ni nwọn nlọ ti nwọn nde bi iṣẹ wọn ni asiko.

Inu wa yio dun ti ọga ọlọpa ba wa mo u lo ... na ni asiko ki nwọn si ba wa ṣe eto ti o daro na ni Agege.

Emi ni,
Agọọrandun,
MUSHIN

gbogbo enia ni ori oju ọrọ nilẹ gbogbo enia ni okorira ihuwasi Oloye Akintọla.

Ofẹrẹ jẹ pe, ko si ẹniti o ni ifẹ Oloye Akintọla lati ọjọ ti o ti kuro ninu egbẹ Afẹnifẹre, Alhaji D. S. Adegbenro e ro ọrọ na daada, ki ẹma fi nkan kekere ba nkan nla jẹ, Iku ti yio pani, ani ... si ni.

Emi ni
R. ADurojaiye
Eko

## Isopọ Dẹmọ Ati Ọlọpẹ

Yio dun mọ mi ninu ti Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi laye ranpẹ ninu iwe rẹ Oloyin mọmọ ti onkọ wa ni ọgbọn ati oye lati ṣe ẹdun ọkan mi si awọn tojade ninu awọniwe Irohinni ede oyinbo ti ọjọ kejidinlogun oṣu karun ninu ọdun yi.



Alhaji D. S. Adegbenro

Loju teme Ọlọla Alhaji D. S Adegbnro ko le ba Oloye S. L. Akintọla ṣepo mọ rara, iya ti Oloye Akintola fi awọn ẹgbẹ na pọju ki Alhaji wa tun ba ṣepo.

Nitocto, ko si eri wipe Alhaji Adegbenro fesi si ọrọ na rara, ti Alhaji na ba nfẹ ilọsiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre nse ni ki o ko patapata Yoruba lo pa lowe pe,ina esisi ki joni lẹmeji. Ifẹ ti gbogbo araiye ni si ẹgbẹ Afẹnifẹre pọju.

Ti Ọgbẹni Oloye S. L. Akintọla lo mu ifẹ na ga nitoripe

## A Nfẹ Iwe Ajiran

Olotu jọwọ gba mi ni aye ni nu iwe rẹ oloyinmọmọ, lati bẹ Ọgbẹni wa J. O Shoyinka ti o nkọ itan Ajiran ilu awọn oku fun wa ninu iwe rẹ lati bi ọsẹ mẹfa sẹhin, eyiti o jẹ wipe o fẹrẹ mo tun si itan ti o dun to ninu iwe Irohin Imọlẹ nitorina a bẹ Ọgbẹ ni wa yi lati ba wa ṣe itan na si nu iwe fun kika awọn ọmọ wa ti o mbọ.

Nitori itan na dun pupọ, o si kun fun orisirisi ẹkọ ti ko ni aba wọn, nitorina inu awa onkawe Irohin Imọlẹ yio dun pupọ bi Ọgbẹni Shoyinka ba ṣe iwe na lẹhin ti o ba ti pari rẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ tan ki o si ma ta wa. ao si ra pẹlu Ọgo Oluwa.

Mo lero pe gbogbo awọn ẹlẹgbẹ mi ni o kin mi lẹhin ọrọ mi yi, ki o le mu ori Ọgbẹni wa na ya lati ṣe iwe na.

Ẹ ṣeun o.

Emi ni,
Mulikatu Oyerogba,
ỌYỌ.

## Itan Yi Dara

Ẹdakun ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe yin alaka kọgbọn ati oye ti o si tun nran wa lọwọ lati mọ ede Yoruba ka dada lati dupẹ lọwọ ọgbẹni J. O. Shoyinka onitan Ajiran Ilu Awọn Oku fun ọgbọn ati oye to wa ninu itan na.

Lati igbati itan na ti njade nmo ti nra iwe Irohin Imọlẹ merinmẹrin nitoripe ọkan le sọnu, mẹrin ko si le sọnu tan.

Itan na nkọ enia ni ọgbọn ati oye o si tun dara fun awọn ọmọ ilẹ Yoruba lati ma ranti isẹdalẹ wọn, nitoripe asa alaṣa ti ba asa wa jẹ Lojojumọ ni awa nko asa tuntun ti a si nsọ asa ti wa nu

Oye awọn ọmọde lati mọ ka ede Yoruba ba le ye wọn yekeyeke osi tun le mọ kọ wọn ni iru wahala ti ọmọ enia nkan ni aye ti awa yi, Lẹkansi mo ki onitan na ku sẹ

Mo tun dupẹ lọwọ lotu to ntẹ iwe na jade fun wa ka.

Emi
J. O. Alao
IWO


BI O BA NI
Iwe—Titẹ
FUN
**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orisirisi iwe itulọ tabi ijade Oku**
ATI
**Iwe gbeyawo**
TETE KỌWESI ILE–IṢẸ–ẸRỌ ITẸWE
**Modupẹ Printing Press**
16, Banigbose Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo Iṣẹkanṣoṣo ko ... ri iyatọ*



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIK

IYALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi sẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa la ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igba-dun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu:a

Waterool Medcine Store
8, Palm Church Street, Lago–
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14' Wakeman Street, Yaba

# Akọrin Ti Ko Ba Ni Ero L'ori, À maa Da Otẹ Silẹ

Lati Ọwọ MAJẸKOBAJẸ

Otun-Oro, ẹku ọpẹlọpọ suru, nigbati mo ranti orin kan ti aşunrara kan kọ fun awọn enia kan ni ọduu idunta ti awọn enia lọ si Yidi nibiti nwọn ti kọrin lati Yidi gba igboro Ọtuu-Oro kọja, asunrara na wa nkọrin si wọn bayi, Ẹnyin ni agbara ojo ti ba ni jẹ, ti o tun ngba ode ẹni kọja Ha! ẹnu ya awọn enia wọnyi. Nwọn dakẹ.

Nipa suru, nwọn dakẹ nwọn bẹrẹ si wo wọn niran nwọn ko gbin rara, ẹuyin ẹnkawe Irohin Imọlẹ afi iran ti gbogbo wa nwọ, ki a bere lati ori balogun de ọdọ awọn enia ti ki şe Balogun to jẹ pe, nigba atijọ ti nwọn mọ lọ si idalẹ awọn ilu bi Ibida Ibadan tabi Ọja Ejinrin lati lọ mọ ra ẹja ati okun mirar.

Nigbana alagbara to wa ni Ọtun-Oro ni yio siwaju ti awọn bi oni rara; yio wa ṣẹle nitori aganigun ko mọ ba mu wọn lojuọna şe ni wa ri orin wọn nisisiyi, nwọn wa di agbara ẹjẹ loni

Iwa ti ko dara ni ki a mọ kọrin bu ara wa awọn alagbara ti aiye atijọ, nwọn sa bimọ saiye, awọn ọmọ wọn na ni agbara ni aiye ode oni. Awọn Yoruba lo npa lowe pe, bi enia ko ba gbagbe ọrọ atijọ oluware ko ni ri ẹnikan ba şere mọ.

Gẹgẹbi onirara na ti ditẹ si Oro, koti kuro ni oro aiye depo pe, yio lọ si oro Ọrun. Awọn obi wa lo npa owe kan pe, ẹran ni mu ni jẹ idin, bi ti panla kọ.

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIAS (Jan 22 – Feb) Maşe binu ṣe iwọ ko ni ba awọn enia rẹ ti o mbẹ nibiti ejina se mọ, nitoripe ko tẹe ẹjọ wọn, maşe şepe fun enia lọjọrọ oni

PISCES (Feb 21 - March 20) Awọn ọrẹ yio wa ki ọ loni, logi egbo alafia rẹ lati ri pe işẹ ti o ti nşe ki o tun bẹrẹ gbe, maşe ojcjo pupọ, şugbọn lọ bulẹ ki o sun orun aarẹ diẹ.

ARIES (March 21 – April) Lo egbogi lati fi da aarẹ ara rẹ duro ki o lo ọgbọn ori niti paapa amọdi rẹ na,

SAGITARIUS (April 21 - May 20) Tun ọkan ati iwa rẹ şe, maşe rope ẹti mimu ni yio mu alafia wa fun Iwọ kogbọdọ da omi ọsa kọja tabi ki o wọkọ oju omi ọkọda loni, Alijanu odo nwa ọ kiri.

GEMINI (May 21-June 21) Ijọgbọn kan yio kọlu ọ loni, Iwọ yio ba ọrẹ rẹ kan ja, nşe ni ki o mu suru, ao si fi asiri nla kan han ọ,

CANCER (June 22-July 23) şọra rẹ, nitori awọn oni keta ati awọn ajẹni lẹhin, ijakadi le bẹsilẹ, bi ọrọ ba da bayi, nşe mi o ma şe akiyesi, iru awọn ọrọ ti yio ma ti ẹnu rẹ jade.

LEO (July 24- Aug 22) Maşe yaju tabi ki o kanra si awọn ọmọ abẹ rẹ inure rẹ yio gbe ọ ga, şọra nitori awọn ni wayo tabi awọn enijibiti dajudaju bi iwọ ko ba şe ju ara rẹ lọ, şiş rẹ yio yọri si rere,

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Ire yio ba ọ kẹgbẹ loni, Adehun kan yio şelẹ larin iwọ ati ẹrẹ rẹ kan ti iwọ pẹlu rẹ ti nfi igba kan ta kọrọngbọn si ara nyin, Ire ni Ọjọ oni yio jẹ fun ọ

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Şọra fun ọrọ bi ija loni ọgbọn ori rẹ ti o nlo ni Ọlọrun gba fun ọ iru iwa bẹ dara fun ẹniti o ndọgbọn ti o si mọ nkan tabi awoian ni yiya

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Itẹlọrun yio wa fun ọ ninu ile rẹ ko ni si edekoyede mọ awọn ọrẹ rẹ yio fẹsẹ mulẹ gbọnin Ma şọra rẹ nigbogbo igba

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Ọgbọn ori rẹ ti o ni, li eyiti yio gbe ọ fo işrokan şoda, laitutẹlẹ duro gbọin gbogbo rẹ yio si dara bẹrẹ lati oni ki o ma sun orun wakati meta lejumọ

CAPRICORN (Dec 22- Jan 21) Akoko yi le fun ọ, ni ọjọrọ oni na, ma reti ere nla kan ti yio jẹ tirẹ.

Bi enia ba fi awọn ti nkọ iwe ikọkukọ sile gẹgẹbi Ọgbẹni Aridẹgbeju ti mo bere titi ti ngo gbọ ohun rẹ ninu Irohin şisi ile ẹkọ ti Oro (Oro Grammar School) mo dupẹ ọwọ Ejongboro to fun mi ni irohin ile ẹkọ giga. On ko jẹ ki a ri edeaiyede larin ilu mẹşẹşan to wa ni ẹkun Oro ati ni ilu miran.


# SEDO — PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun "Ipara" ti awọn ilera tabi amọdi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu lode ara, ọwọ tabi ẹse hihun tabi yiyun nigbakugba, Aifọ, Egbo esẹ orişirişi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ bi adarin egbo ekusẹ tabi ekusẹ tabi lapalapa, Ela tabi ara sisu,Akọ, inarun ati orişirişi arun "Ara" miran gbogbo





Gbiyanju lati da egbogi fun awọn ara Ilu Tatanbu bẹlu şe ti nwọn npe ni "PAYAL" wọ larin ọjọ mẹta wọ na yio ma rohin rẹ fun awọn elomiran pẹlu Egbogi para yi ki şe awọn tọhiru bi ti wọn nta kakiri ilu ni owo poku. Ojulowo egbogi arun arun ara hanuhaun ti ko si eişe ye meji ninu eleyi si yatọ patapata si awọn ẹgẹrẹmiti adimọwọ ti wọn nta kakiri igboro ati ni agbereko gbogbo pẹlu Orisi meji rẹ lo wa. Kekere ati Nla.

Bere egbegi Ajẹbi lan SEDO PAYAL yi ni şọbu awọn:

PILENAB MIXTURE,

Egboigi olomi dara julọ fun awọn ọmọde ti jedijedi bi ako gborse dede ba nyọ lenu bere rọ ni

WATERLOO MEDICINE STREES
FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.



# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MODUPE PRESS
*Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgbose Street,
Phone 21985, Lagos

